# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 929 LAGOS SATURDAY JULY 11—JULY 17 1964 KỌBỌ MEJI (2D)

### Awon Ibo Gbalejo Apapandodo:

# Ijoba F'aropileni Oru Gbe Oloye Awolowo Lo Si Kalaba

KALABA – Ni oru ọganjọ, ni iwọn nkan bi agogo mẹta oru nigbati gbogbo awọn enia ti sun ni a gbọ wipe awọn ọga ọlọpa ati dẹrẹba ọgba ẹwọn kan ilẹkun ibiti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, ẹniti o nṣe ẹwọn ọdun mẹwa rẹ lọwọ, wipe ki o mura, nwọn si gbe sinu mọto, nwọn wa a gba Ikẹja lọ nibiti nwọn gbe;ti gbe e lọ sinu aropiloni ti o wa a lọ si ilu Kalaba awọn wọda ile-ọgba ẹwọn. Gẹgẹbi ọrọ ti akọwe onirohin wa gbọ nigbati o nṣe iwadi lori ọrọ na ni iiẹta, a gbọ pe Oloye Frank Giwa Osagie ti o ṣe ọga agba pata fun eto iṣẹ ile awọn ẹlẹwọn ni o paṣẹ pipa ipo Oloye Awolọwọ da, gbogbo awọn yo ku ti kotu giga kọ ẹbẹ wọn lort ẹwọn ti nwọn nṣe lọwọ ni wọn yio tun pa nipo da bakanna nigbakugba ti aye ba ti ṣi silẹ ninu ile ọgba ẹwọn ijọba apapọ ti nwọn wa ni ilu okere.

Ọga awọn dẹrẹba wọda ti nṣe alaṣẹ ọgba ẹwọn na nsọfun oniwe irohin wa pe gbigbe Awolọwọ kuro ni Eko ni id , ati pe on ko le gba ki gbogbo awọn arufin na wa ni ilu E o nitori alafia ijọba ati pe wọn ko fi ẹwọn tabi pakute mamugari si Awolọwọ ni ọwọ rara ninu irin ajo rẹ si Kalaba gbẹfẹ ni awọn ruu lọ wọkọ ofurufu nitoripe awọn ẹlẹwọn ti nwọn ba nṣe orikunkun nikan ni awọn ma nfi ẹgba pakute si lọwọ.



Oloye Obafemi Awolowo
AṢIWAJU ẸGBẸ AFẸNIFẸRE

## Alufa Orieru Ku Sori Awo Ikirun

IBADAN—Ariwo ta u u ni Agbo ile kan ti nwọn npe ni A anku u ni Orieru ni aṣalẹ ijẹta nigbati awọn ara adugbo gbọ iku Alufa an, Tijani Alamu ti o u lo.iji lori awọ ti o fi nki irun magarubi lọwọ.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lọdọ awọn ẹbi alufa na, nwọn ni o ṣẹṣẹ di ọmọ ẹgbẹ oṣe u ẹgbẹ Dẹmọ ni o si lẹ iwe ẹgbẹ na ti wọn ya ọwọ si mọ ẹnu ọna ile rẹ, ṣugbọn lọjọ kan ni awọn jandu u an ni adugbo wọn wa fa iwe na ya.

Eleyi mu Alufa Alamu ologbe yi lọ fi ẹ ọ awọn janduku yi sun'ni teṣan awọn ọlọpa ni Gbagi.

A gbọ wipe bi o ti pada dele pẹlu awọn ọlọpa lẹhin ti nwọn wa ko awọn ti o tọ asi wipe awọn ni nwọn ya iwe ẸGBẸ ỌLỌWỌ ti o fi yẹle, ti o sare gb'awo wipe ki on tete sare ki irun MAGARUBI ni Ọlọ,ọ de ba a.

Awọn Ọlọpa koi 'ti pari iwadi ọrọ awọn enia ti o wipe nwọn nyọ on lẹnu i nwọn to gbọ wipe Alufa na ti ku.

# Omo Egbe Demo Wo Ijakadi Pelu Awon Olopa

GBỌNGAN — Ninu ijakadi nla kan ti o bẹsilẹ larin awọn ọmọ Ẹgbẹ Dẹmọ ati awọn ọlọpa ti nfi ọkọ ofurufu fimu finlẹ kaxiri ni ọna ilu Ibadan ati Gbọngan ni ọsẹ ti o kọja a gbọ, irohin wipe enia kan ku bamu bamu, awọn mẹkanla miran ninu wọn ṣeṣe lọjọ na.

A gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ na wa ninu mọto awọn akero kan ti nwọn lọwọ tẹle Oloye R. A. Fani Kayọde lehin lọ si Ile Ifẹ fun ipade kan. Awọn ọlọpa ni nwọn ko kunmọ ati nkan ija lọwọ nigbati awọn pade wọn ti awọn da wọn duro lati gba gbogbo nkan ti nwọn le fi ṣe enia lọṣẹ lọwọ wọn.

Ninn ija'adi na, a gbọ pe moto bọlugi (Jeep Cars) meji ni nwọn bajẹ kọja titunṣe, nwọn si pa wọn ti si ẹ ba ọna, Ọgbẹni Latifu Makinde, ọmọ agbole Ọrunto ni Ile-Ifẹ ni oruk ẹniti nwọn sọ wipe o na njẹ a gbọ wipe nwọn gbelọ si ile awọn lakuku Adeoyọ ni Ibadan, awọ miran ti nwọn ni ifarap pẹlu ori fifọ ni nwọn si ajo fun ninu ile-iwosan nwọn si ti da wọn silẹ.

G.ad'igb. yi bẹsilẹ nig ti awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹ na npada bọ lati Ile-Ifẹ ilu Ibadan pẹlu ọpọlọp mọto pẹlu Oloye Fani K. yọde, igba eji Olotu ipin iwọ Orun ati alakoso ijọ Ibilẹ.

Irohin ti fi nye wa pe bi igba keji Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun yi ti gunlẹ si Gbọngan pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ na ni agogo mẹrin ẹ a iṣẹju mẹdọgbọn ni awọn ọlọpa onihamọra ija ba yọ lati ọna ti o ti Ibadan wa, nwọn ba fi mọto wọn dẹbu ti ẹgbẹ Dẹmọ.

Wẹrawere, Oloye Fani-Kayọde ti fo bọsilẹ ninu mọto tirẹ lati ba ọga awọn ọlọpa na sọrọ, ṣugbọn lẹnu ọrọ yi ni ija ti bẹsilẹ, ija na si jẹ eyiti o burujulẹ.

Oloye Fani Kayọde so pe bi ṣoogbo nkan ti lọ si yi, on o ni ni gbolohun kan lati sọ, ṣugbọn awọn ọlọpa ti ṣe alayẹ ti wọn lati ile iṣẹ awọn ọlọpa, nwọn ni lori nkan ti o ṣẹlẹ ninu ijakadi na ni agbegbe Ibadan ati Ile-Ifẹ awọn ọlọpa ti gba awọn enia mẹsan mu, fun ẹsun wipe nwọn ba awọn ohun ọsẹ lọwọ wọn ni nkan bi agogo mẹrin-abọ ni irọlẹ ọjọ karun oṣu yi.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Ijoba Ti Ko Awon Soja Nigeria Pada Lati Kongo

IKẸJA — Ogunlọgọ awọn ṣọja ilu wa ti awọn alakoso Ijọba Nigeria ti fi igba kan ko lọ si ilu Kongo (Congo) lati lọ ran wọn lọwọ fun rogbodiyan ti o bẹ silẹ ni ilu na ni nwọn ti ko pada si Nigeria ninu ọsẹ yi.

O ti di ọdun mẹrin gbako nisisiyi ti awọn alakoso ajọ igbimọ apapọṣe agbaiye ti nko ogunlọgọ awọn ṣọja lọ ilu Kongo lati ran Ijọba ibẹ lọwọ. Bi awọn alamojuto Ijọba ilẹ Nigeria ti fi ṣọja wọn ranṣẹ ni nwọn tun ko ọpọ ọpọ awọn ọlọpa lọ.

Ni ijẹta ni awọn alakoso Ijọba ilu Gẹẹsi paapa ko awọn ṣọja ti wọn paapa kuro nibẹ. A gbọ wipe gbogbo nkan ti nrọ kakiri ilu Kongo a fi ni ilu Oke ibẹ ti a gbọ wipe awọn pa Ọgbẹni Jason Sendwe tiṣe balẹ Ijọba apa oke Katanga.

Awọn amọye kan ni iwa buruku yi le jẹki awọn ara ilu Ọgbẹni Sendwe le dide wipe awọn fẹ ja lati gbẹsan lara awọn ara ilu ti nwọn pa ọkunrin na laipẹ yi.

## Ojo Ibi Ojo Ayo



IBADAN — Oloye Samuel Ladoke Akintọla, Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun ni ilẹ Naijiria ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ṣe ajọyọ iranti ọjọ ibi rẹ ni ana Ọjọ Ẹti ti nṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni ilu Ibadan fun pipe ẹni ọdun mẹrinleladọta.

Eto fun oriṣiriṣi awọn ere ariya ni nwọn ṣe lati fi damuso fun Oloye Akintọla ni ilu Ibadan, Ẹena ni ọpọ awọn ọrẹ ati olufẹ rẹ jakejado ilẹ Nigeria ni nwọn ti lọ si Ibadan lati ba ṣe ajọyọ ariya ọjọ ibi rẹ.

A ki Oloye Akintọla pe o ku ori rẹ, ki Olọrun jẹki o le ṣe ọpọlọpọ ọjọ ibi bayi, ki o si fun ni ẹmi gigun ati alafia.

# Ara Ilu Aganyin Kan Gbe Owo Ijoba

ACCRA — Ọjọ Aje tį nşe ọjọ kọkandinlọgbọn oşu ti o kọja lọ ni irohịn kan wa wipe ọmọ ịlu Aganyin kan tį o jẹ onişowo, ti orukọ rẹ sį njẹ Henry Kwadjoe Djaba gbe owo tį iye rẹ jẹ ọkẹ mẹwa pọun (£2,000000) ti nşe ti ịle-işẹ onisowo ẹrọ agbẹ kan ti o si jẹ ti Ijọba ịlu Ghana, nwọn si duro fun ni ọkẹ kan pọun (20,000) nį kete ti o ba ọkọ ofurufu pada si ilu rẹ lati Londọnį.

A gbọ pe Ọgbẹnį Djaba, ẹniti o ti jẹ ọga Olutọsọna ninu ile-işẹ awọn ẹgbẹ ti nta awọn ịrinşẹ fun işẹ agbẹ şişe ni ilu Ghanna tẹlẹ ri ni o nfoju wina awọn esun mẹsan kan lati ọwọ awọn ọlọpa eyįti o jẹ mọ ịrẹjẹ lọna eru ati şişe madaru sinu iwe ịşiro owo ẹgbẹ onisowo na, ti o to ọkẹ mẹwa pọun, (2,000000).

Kotu ko tį bilere lati şe alaye kan rara, şugbọn o danilojupe on yio tun farahan nįwaju adajọ ni aipẹ yi.

# Olugbimo Kan Wewon Odun Marun

AKURẸ — Lẹnu lọ'ọ yi ni a gbọ pe adajọ kotu kekere kan ni ilu Akurẹ sọ olugbimọ kan (Councillor) Ọgbẹni Oni, ẹni ọdun mejidinlọgbọn ti o tun jẹ ọkan ninu awọn igbimọ Ifẹdọrẹ nitosi Akurẹ ni agbegbe ilu Ondo sẹwọn ọdun marun lori ẹsun ịwa ibajẹ,

Awọn ọlọpa sọpe Ọgbẹnį Onį jẹbį fifi ailẹtọ gba pọun marun ( £5 ) lọwọ ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Alu Muibi lori ẹjẹ pe on yio lo ịpo on gẹgẹbi olugbimọ lati ba wa ịşẹ nọsi-ẹkọşẹ eyịti aşẹ atį akoso rẹ mbẹ lọwọ ile-işẹ ti igbimọ Ifẹdọrẹ.

# Awon Olopa Ilu Oku Alawo - Opa Kan Ni Ijebu-Igbo

IJEBU IGBO —Adugbo kan ti nwọn npe ni Okesọį nį ilu Ijẹbu-Igbo jẹ orisun ibẹru-bojo fun ... ni ọsẹ to kọja nįgbati nwọn nworan bi dokita ...şegun kan duro ti ọlọpa kan tį o hu agebu ara o'u kan jade latį inu ilẹ.

Oku tį nwọn sọ dį alabọ ara yį nį awọn ọlọpa sọ pe awọn gbagbọ pe yịo jẹ tį Ọgbẹnį kan ẹni ọdun mejịdinọgọta (58 years) ti orukọ rẹ njẹ Amusa Adekoya, ti o si tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ alawo-ọpa kan ti nwọn npe ni Ọbagoroye nkan tį o si fi nşe ọmọkunrịn nį nwọn ti ge kuro kį nwọn to sin.

Nwọn ni onilati jẹ pe ẹmį ọmokunrin ti ọwo awon enia kan bọ ni, şugbọn awon ọlọpa tun fi han daju wipe enia, diẹ nį awon tį hamo ịt mole fun wįwa apįdi oro na, şugbọn nwọn şį fi orukọ ho wọn laşiri na. Ẹo tun ma gbọ nįpa rẹ nį ọsẹ tị mbọ.

Ohun ti o tun fa lifi iwe pe Meyọ yi si ibi ... yį nį pe ọpọlọpọ ... awọn oşişẹ ile işẹ kansolu (L, C, C ) ni ilu Eko ... o jẹ pe awọn ti gba ẹkọ giga wọn lati ịlu Hull ... ilu Oyinbo.

# Awon Omoge Olo ko Ofurufu Ja Ija Alailojuti Ni Ilu Oyinbo

(O bẹrẹ loju ewe kota)

Ẹnikan ninu awọn ero tį o ba ọkọ ofurufu wọn de lati ilu Oyinbo, ti ja wọn na şe oju rẹ ni awọn ko le sọ nkan ti o faja ... o ni bi enia ba gba ... wọn lọkọ ija na ko le ... to bẹ rara. O nį ... ọmọge na ti gbagbe wịpe ịlu ajojį ni awọn wa.

Nwọn ni orişịri ebu ... nwọn bu ara ... ọn ... tun faşọ mọ ara wọn ... nşe ni awọn Oyinbo ... wọn şe iran wo.

Şugbọn gẹgẹbi irohin ti a gbọ nisisiyi, nigbati o di ọjọ Aje (Monday) ti nşe ọjọ ... oşu yi ni awọn alakoso ile işẹ ọkọ ofurufu ni Lẹgọs ni ilu Eko fi iwe idaduro fun awọn ọmọge mejeji na fun iwa aikasi ati ọmugọ ti nwọn hu.

Ninu iwe idaniduro lẹnu işẹ ti nwọn gba, awọn alakoso si ... fun wọn pe iwa ti nwọn hu ni ibudo ọkọ ofurufu ni Londọnį mpa ijakadi ti nwọn ba ara wọn ja jẹ eyiti awọn awọn kasi pe o je abuku fun ilẹ Naijiria ati ile işẹ ọkọ ofurufu ti ilẹ Naijiria.

# Won Fe Si Oja Ebute-Ero Titun Ninu Osu Yi

(O bẹrẹ loju ewe keta)

fun ni anfanį latį ni ipin ninu awọn isọ ti nwọn wa nįbẹ.

Awọn ẹgbẹ kọlekọle patakį meji ni nwọn gbe işẹ kikọ ọja na le lọwọ awọn nani Harola Shodį pọ atį Jammal Engineerịng Company nwọn ti pari kikọ ọja na lati oşu kejịla ọdun 1963.

Ninu awọn ti nwọn ti fi iwe ke fun aşeyẹ ọ ọna ni ọlọia Mayọ kan lati ịlu Oyinbo Meyọ ilu Hull ẹniti orukọ rẹ njẹ Alderman F. Hammond nitori ibaşepọ ti o wa larin igbimọ awọn alabojuto idagba soke tį ilu Eko pelu ilu Hull na.

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT DRIVER



# ELETI-OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos; "ELETI-ỌFẸ" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 929 SATURDAY July 11 — July 17 1964


## ORO OLOTU

# E Fe'yi Kogbon

Nwọn ni o yẹ ki a ma ba ẹniti o ba nsọkun sọkun, o si yẹ ki a ma ba ẹniti o ba nyọ yọ. Inu awa onirohin Eleti-Ọfẹ dun pupọ lati ba ara ilu wa, Alhaji Mahmud Dantata Hausa onisowo kan ni ilu Kano, ti awọn Ọlọpa ba ṣe ẹjọ nipa owo agbelẹrọ ni Ipinlẹ Ariwa ni iwọn nkan bi ọdun meje sẹhin, ti nwọn si jẹ niya lori ọrọ, ti a gbọ wipe nwọn darijin, nwọn yọ knro lọgba ẹwọn ni ijarun.

Itimọle ko kọ ẹnikan, o ko ba jẹ Olowo tabi talaka, A ko kọ ọrọ Olotu wa tọsẹ yi lati fi yọ ẹnikan ṣugbọn lati fi ọrọ Alhaji Dantata ti o sọ nigbati o jadẹ ninu ọgba wahala yi kọgbọn,

Alhaji Dantata ni on mọ gbogbo awọn ti mba on jẹ, ti nwọn mba on mu, ti nwọn ko ba on, ṣugbọn ju gbogbo rẹ lọ, on dari ẹṣẹ wọn jin wọn.

Alhaji Dantata ni bi a ba ṣubu a ni lati mọ ẹru wa di. O ni a lọ sẹwọn ko wipe ki a ma ṣe iṣẹ-rere ti Ọlọrun ran ni bi ẹda si awọn ẹni eji ẹni. A gbọ wipe gbogbo igba ti o wa lọgba ẹwọn ni Alhaji na nfowo tọre fun arufin ti nwọ njade lọgba ẹwọn wipe ki nwọn le ri mu jẹun, ki nkan oninkan ma le wọ wọn loju.

O YẸ KI A FI EYI KỌGBỌN, ẸNYIN ARA WA, Alhaji Dantata ko duro nibẹ, o ni on tun fẹ da iṣẹ agbayanu kan silẹ fun ọpọlọpọ awọn enia ti ko ri iṣẹ ṣe.

Solomonu Ọlọgbọn ti sọ ọrọ tan ninu iwe rẹ, o ni "NIGBATI O BA NṢE RERE FUN OLODODO, ILU A YỌ" A ba Alhaji Dantata yọ, o ku inure, o ku orire. Ẹ fi ọrọ re kọgbọn.

# Iwe Si Olotu

# Eyo Sise Ni Ilu Eko

Inu mi yio dun bi Olotu iwe irohin Eleti-Ọfẹ ba le gba mi laye ninu iwe rẹ ti o nta iwẹlẹwẹlẹ bi akara gbigbona lati dahun si ibere kan ti Mallam Yisa bere ninu iwe Irohin Imọlẹ t ọsẹ ti ọjọ keji oṣu yi wipe-Njẹ o yẹ ki a ma ṣe Ẹyọ ni ilu Eko? O tun sọ pe ere Ẹyọ ko dara.

Ṣugbọn inu mi yio dun ti Ọgbẹni Hausa na ba le ranti pe gbogbo wa ni a ni orișa idile tabi ti Ibilẹ wa lọtọtọ, ati wipe nwọn ti bẹrẹ ere Ẹyọ ni Ilu Eko ni ikan bi ọgọrun ọdun sehin, ko si tun si ere ibilẹ miran mọ ti o ju ere Ẹyọ lọ ni ilu Eko.

Gẹgẹbi Ẹyọ ti ṣe jẹ orișa ibilẹ wa, wọn a ma ṣe ere yi lati fi ṣe ẹyẹ aasa fun iranti ẹniti o ba ti ku ti o si ti jẹ eni pataki ni ikboro ilu Eko ati aṣiwaju pataki ninu ẹgbẹ Ẹyọ.

Bi Mallam Yisa iba ri wipe nwọn na on pupọ ju, ki o ma lu ofin Ẹyọ, nitori bi enia ko ba lu ofin Ẹyọ ko ni gbọn otutu ara rẹ nu lati ọwọ apambata awọn Ẹyọ. ko si ere miran to tun larlorin bi ere Ẹyọ ni ilu Eko b ni ko si dara lati parẹ nitori orișa ibilẹ ilu Eko ni.

Emi ni tiyin,
Eko Saka Adetayo

## Aditi Kan Gboye Eko Giga Ni Ilu Oyinbo

WASHINGTON— Akẹkọ kan ti orukọ rẹ njẹ Seth Lawrence Tetteh-Ocloo, ti o si tun yadi, ti o si jẹ ọmọ ilu Ghana ni a gbọ irohin nipa rẹ pe o ti yege ninu ẹkọ ijinlẹ rẹ o si ti gboye ẹkọ giga lori iṣẹ ọgbọn ori ni ile ẹkọ giga kan ti nwọn npe ni Gallaundet Arts College ti nṣe ile ẹkọ giga kanṣoṣo fun awọn akẹkọ ti o yadi ni gbogbo agbaiye ni ilu awọn ara Amẹrika ni Washington.

Ọgbẹni Tetteh - Ocloo ni ẹniti o jẹ ọmọ ilẹ enia dudu ti o kọkọ ma gba iru oye bayi ni ile ẹkọ giga na o si ti gba iwe ẹri rẹ perepere, eyiti Babasalẹ Ọgbẹni Johnson ti o jẹ olori ile ẹkọ giga na ti fi ọwọ si lẹhin ti o ti pari eto ẹkọ rẹ fun ọdun mẹta gbako.


# Eleti-Ofe D'araba

A NFẸ AṢOJU NI AWỌN ILU YI IBADAN, ABẸOKUTA ỌYỌ AWẸ ati OGBOMỌSHỌ.

# E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI-OFE

ti o kun fun irohin aladun lososo.

# Adajọ Agba Tẹmbẹlu Awọn Agbẹjọro Ijọba Ni Ibadan

IBADAN—Ọgbẹni Olujide Shomolu, adajọ kotu giga kan ni ilu Ibadan ni a gbọ pe o fi ọrọ ẹnu tẹmbẹlu awọn agbẹjọro (awọn lọya) ti nwọn ma nṣe lagbasọ fun awọn ile iṣẹ ijọba ni ipinlẹ Iwọ orun lori ọna ti nwọn ngba fi ṣe ẹjọ fun awọn ile-iṣẹ ti o gba wọn sise.

Adajọ agba na sọ pe iṣẹ gbigba ẹjọ ro fun awọn ile-iṣe ijọba ni Iwọ Orun jẹ ohun ti o ku diẹ ki a to, o ni ki o ma dabi ọrọ afojudi o n nilati jẹwọ pe ni akoko yi, bi awọn agbẹjọro Ijọba na ti n'gba ṣe iṣẹ wọn ko dara rara.

Ọrọ akiyesi yi ni adajọ agba na sọ laipe yi ki o sun gbigbo ẹjọ kan ti ọgbẹni Jimọ Abimbọla pe ile iṣẹ ijọba ipinlẹ Iwọ Orun kan siwaju nititi on Jimọ papa ti jẹ ọkan ninu awọn oṣiṣẹ ibẹ fun didaduro lẹnu iṣẹ laindi, lori eyiti Jimọ si nfẹ gba Ẹgbẹdọgbọn poun (£5,000) lọwọ awọn alakoso ile iṣẹ na gẹgẹbi ọwọ irinsẹ ati ipalara ti ididuro na mu ba on.

Ninu kotu giga na ọgbẹni R. O. A. Akinjide sọfun adajọ pe on yio ṣe agbẹjọro fun ile-iṣẹ na adajọ si wa sọrọ idunnu pe o je iwuri fun on lati ri pe enia bi ọgbẹni Akinjide ni yio ṣe agbẹjọro fun ile-iṣẹ na.

Ọgbẹni Abimbọla ti o ti jẹ ọga kan ninu ile ise kan ti nwọn npe ni W N D C, ti o si ngba okoolelẹdẹgbẹrin poun (£720) lọdun ni nwọn da duro lẹnu iṣẹ ninu ọdun yi lori ẹsun wipe o n ni imọ lori ole kan ti nwọn ja nibi iṣẹ on ti nwọn fi gbe mọto akẹru kan lo bamubamu.

Abimbọla sọ sinu iwe ipẹjọ rẹ o ni nwọn da on duro nitoripe on kọ lati ṣe ẹgbẹ Dẹmọ tuntun ti nwọn ṣese da sile ni Ibadan ni Adajọ Shomolu fi sun ọjọ gbigbo ẹjọ na si iwaju.

# Direba Olori-kunkun Kan Kosi Pakute Awọn Ọlọpa

IJẸBU-ODE:- Ni ọjọ Ajẹ ti nṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ri Kotu ibi ẹ agba kan ni ilu Ijẹbu-ode paṣẹ pe ki direba mọto kan ti oruko rẹ njẹ Safiriu Arogun o de fi poun marun dinladọta (£45) tan ọran tabi ... ṣe ẹwọ oṣu mẹfa pere lori ẹsun wipe o ... wa mọto rẹ ni ọna ti o mu ipanilara dani.

Ọlọpa ti o mba Arogun dade ṣẹjọ sọfun kotu wipe ni ọjọ ti Gomina Ipinlẹ Iwọ orun ọlọla Odẹyẹ Fadahunsi ati awọn ẹnẹwa rẹ nkọja lọ ni opopo kan ni Ijẹbu-Ode si ilu Ẹpẹ ninu oṣu ti o koja lọ yi awọn ọlọpa aloore ti ngun alupupu paṣẹ fun dẹrẹba na lati duro si apa kan ọna sugbọn ka a ki o duro nișe ni o fi gbigbọ se alaigbọ lẹhinna o tun wa mọto na ni iwakuwa ati lọna to le fi mu ipalara wa enia o tilẹ fẹrẹ fi mọto rẹ kọlu mọto Gomina papa. Ninu ... awọn ọlọpa ri ... nwọn bi gba tẹle titi ... wọn fi ẹ ti awọn si mu'ọ si ọgba awọn ọlọpa.

Adajọ ti o da ẹjọ na, Oloye Abiodun O... sọ pe ẹsẹ ti o buru ju ni lati se aigboran si ofin tabi ki lọ awọn ọlọpa ni pa didari awọn mọto o se iki ọ pe ẹni yo u ti nwọn ba tun mu fun ẹbi iru ẹsẹ bayi yio kan agbako ... a ti o nipọn.

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọle

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayọ o lè ri rà nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, iná-titàn ati lati mã fi yiná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ..

# Obinrin Kan Bi Ọmọ Ti Ko Ni Ahọn

EKO – Ninu ile igbẹbi ọmọ ti erekusu ilu Eko ni a ti gbọ pe ọmọbinrin bi ọmọ ikoko kan lai si ahọn lẹnu rẹ.

Ẹnikan ti nkan yi ṣoju rẹ fi nhan wa pe, nigbati iya rẹ ti o jẹ ọkan ninu awọn nọọsi bii ninu ile igbẹbi ni ọsẹ ti o kọja, ọmọ na ko ke rara, ṣugbọn nwọn kan mọ ṣa wipe o wa laye nipa mimi ti o nmi ni.

Awọn oṣiṣẹ ile-igbẹbi sọ pe awọn yio gbidanwa lati wadi ohun ti o fa alebu si ara ọmọ na ki awọn ba le mu ki iru rẹ ma le tun ṣẹlẹ mọ.

Dokita kan ti o nṣiṣẹ ninu ile igbẹbi na sọ pe on ni royiroyi ọkan wipe bi ọmọ na bale dagba pẹlu iru alebu bayi, yio yadi ko si ni le sọrọ rara laisi ahọn.

Irohin na tun sọ wipe ọmọ na nṣe daradara labẹ itọju awọn Dokita, ṣugbọn iya rẹ ti o jẹ ọkan ninu awọn nọsi ti nwọn nṣiṣẹ ni ile iwosan gbogbo-gbo ti damu pupọ nipa ọmọ na, o si to ọjọ diẹ lẹhin ti o bi ọmọ na tan ki on papa to mọ nipa alebu ara ọmọ rẹ.

Titi di isisiyi, awọn Dokita ile igbebi ọmọ ko ti sọrọ kankan nipa ọmọ na, ṣugbọn ẹ o si ma gbọ nipa ohun ti nwọn yio ṣe lori ọmọ na laipẹ yi.

# Eleri Awon Olopa Kan Pada Di Ole

IJẸBU — ODE Ọgbẹni kan ti orukọ rẹ njẹ Mustafa Oguneko, ti o tun jẹ onibara ninu ofofo ṣiṣe ati ẹlẹri fun awọn ọlọpa ninu ẹjọ aibalẹ ọkan kan lori ṣiṣe ibura awo imulẹ fun awọn ọlọpa mba ṣẹjọ laipẹ yi ninu kotu ibilẹ agba kan ni Ijẹbu-Ode fun ole jija.

Gẹgẹbi nkan ti awọn ọlọpa sọ, nwọn ni Mustafa ji pọnun mẹwa (£10) gbe lọwọ Iya Afin Muibatu Ọladipọ ti nṣe iyawo Ọgbẹni Ọladipọ Onitọlọ ẹniti awọn ọlọpa tun mba ṣẹjọ papọ pẹlu Mustafa ninu kanna lori ẹsun ṣiṣe ibura awo imulẹ fun awọn ọlọpa obinrin mjei kan.

Ọga ọlọpa alafisun kan (Prosecutor) ti o njẹ Paul Igori fi ibere wadi alaye ọrọ lẹnu Muibatu nigbati o njẹri ninu apoti ẹjọ, ati ninu ẹri Muibatu, o sọfun kotu pe, on wa lẹnu ẹkun sisun lọwọ fun gbigbọ ti on gbọ pe awọn ọlọpa ti ti ọkọ on mọlẹ, nigbati Ogunẹkọ de wa ba on ti o si bere fun ogun pọnun (£20) lọwọ on lati fifun ọlọpa ti yio tu ọkọ on silẹ kuro ni itimọle ki nwọn ba le duro fun.

Muibatu tun sọ siwaju pe lẹsẹkanna ni on ti lọ ba awọn ẹbi on ti on si gba pọnun mẹwa (£10) eyi ti on ko fun Ogundẹkọ fun itusilẹ ọkọ on, ṣugbọn nigbati awọn de ọfisi awọn ọlọpa tan, Ogunẹkọ tun nwọ inu iyẹwu miran lọ, nigbati o jade, o si wa sọfun awọn pe "Mo ti pari iṣẹ na.

Ki o to di pe Muibatu pari ẹri niwaju kotu, o ni, o wa ya awọn lẹnu pe awọn ọlọpa ko tu ọkọ on silẹ rara titi fun ọsẹ kan gbako ki ẹjọ na to de kotu. Awọn ọlọpa ko ti pari ẹjọ na, ṣugbọn ẹ o tun ma gbọ aṣepari ẹjọ yi laipẹ ọjọ.

# Nwon Fe Si Oja Ebute-Ero Titun Ninu Osu Yi

EKO—Irohin kan desi eti igbọ wa laipẹ yi wipe awọn alaṣẹ ile-iṣẹ igbimọ awọn alabojuto eto ilera ati ida gbasoke igboro ilu Eko fẹ si ọja Ebute-Ero titun, eyiti nwọn fi ọkẹ mejila le le lẹgbarun pọun (£250,000) kọ ni ọjọ kedogun oṣu yi ati wipe Ọba Adeniji Adele Keji ni yio se ẹye ṣiṣi ọja titun na.

Gẹgẹbi ohun ti a gbọ, nwọn ni eto ṣiṣi ọja titun yi tikan ni yio jẹ nkan kan pataki ti yio miringindin ninu ẹyẹ ọjọ na ati eyiti yio jẹ aasa fun siso igboro Eko di ilu nla ati pe ere ẹyẹ fun ṣiṣi ọja na yio bẹrẹ lati ọjọ kẹrinla titi di ọjọ kedogun oṣu yi.

Apapọ awọn ileitaja ti o wa ninu ọja nla na jẹ ọrinlelẹgbẹrun (1,080 stalls ati peowo mehaya fun isọ kọkan bẹrẹ lati ṣile mẹdogun titi de pọun mẹta loṣosu.

Nwọn ni awọn obinrin ọlọja ti nwọn ti ntaja ni bẹ tẹlẹri ti nwọn si ti ko wọn lọ si ọja Oko-Awo ninu oṣu kẹsan ọdun 1961 nigbati nwọn ṣẹṣe fẹ bẹrẹ si kọ ọja na ni wọn yio

(Wo yoku loju ewe kefa)

## Awon Omoge Olo ko Ofunfu Ja Ija Alailojuti Ni Ilu Oyinbo

LONDON — Meji ninu awọn ọmọge ilu wa ti nwọn mba ọkọ ofurufu kiri ni a gbọ wipe nwọn ja ja-alailojuti kan ni ebute ti awọn ọkọ ofurufu ngulẹ si ni ilu Oyinbo ninu ọsẹ yi. Orukọ awọn ọmọge na ni Paulina Oji ati Grace Ozoemena.

A gbọ wipe ija na pọ tobẹgẹ ti awọn mba ṣiṣẹ ninu ọkọ ofurufu ni lati ru wọn pada wa si Eko lati wa sọ tẹnu wọn.

(Wo oju ewe kefa)

# Ina Jole Ni Ekule Abari L'Eko

EKO — O ju ojule mẹdọgbọn lọ ti ina jo bamubamu ni agbole Abari ni Ẹpẹtẹdo l'Eko ni oru ijẹrin, o si tu igba enia lọ ti ẹru wọn sofo ninu ina na. Awọn ara adugbo ni ogun ẹfọn ti ẹnikan fi nfin ile ni o da ijamba ina na silẹ.

Nwọn ni ni igbati ina na bẹrẹsi jọ, ọmọdekunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Seda Alao ti o sare wọ iyara wọn lọ lati ko ẹru rẹ ninu ile fa-rapa nigbati o bọ si ita, nṣe ni o daku gbonrangandan awọn panapana ni nwọn gbe digbadigba lọ si ilẹ awọn alamodi.

Gbogbo awọn ti nkan wọn jona ti nwa sibẹ lati wa ṣa awọn ajoku nkan ti nwọn jona na pẹlu owo ti nwọn ri mọlẹ lati aiyemaiye.

Eleyi ni o di ẹkeji ti ina jo ninu oṣu yi ni Eko. Eyi ti o kọkọ jo ni ti Ebute ọkọ elefin ni Apapa ni ọsẹ ti o kọja. Gbogbo ẹru owu ti nwọn fi nhu aṣọ ti nwọn fẹ fi ranṣẹ si ilu Oyinbo ni ina na jo bamubamu,

**AKIYESI** Fun anfani ẹniti o mọ itan Oloyinmọmọ ti o kunfun ọgbọ tabi itan ilu rẹ, ki o kọ ki o ranṣẹ fi si OLOTU ELETI—ỌFẸ, 28, Kosoko Street, Lagos.



In "African Forum"

# BBC Director - Genral Interviewed

LONDON—Sir Hugh Greene, Director-General of the BBC, making one of his rare microphone appearances has accepted African Forun's invitation to answer questions put by Africans in London in the program me to be broadcast on Wednesday July 15, in the BBC African Service.

Since 1960 when he became Director-General, Sir Hugh has developed a close association with overseas broadcasting organisations, particularly in the Commonwealth. Speaking at the Commonwealth Broadcasting Conference in Canada last year at which Nigeria, Ghana, Sierra Leone and Tanganyika were represented Sir Hugh stressed the value of broadcasting as a means of understanding between peoples, declaring 'there are few tasks which the BBC regards as more important than its Television and Sound services for the British public, and its External Services for the Commonwealth and the world.'

The African Service is an important part of the BBC's External Service and with the BBC Director-General as its guest speaker 'African Forum' this week expands on this theme when the subject will be 'the BBC at Home and Abroad' Listeners can expect a lively and searching enquiry on broadcasting's contribution to the major challenge of our time, communication and understanding between peoples

This special programme can be heard in the BBC African Service at 11.33 GMT on Wednesday July 15 on 21 and 17 megacycles in the 13 and 16 metre bands

Following will be the programmes in BBC African Service during the coming week, after the NEWS at 11. 00 GMT on 17.81 and 21.61 megacycles in the 16 and 13 metre bands:

CILLA BLACK whose latest recording 'YOU'RE MY WORLD' recently topped Britain's hit parade s interviewed in her dressing room at the London Palladium by PETE MYERS for the BBC African Service programme LONDON FANFARE.

Twenty-one pretty natural, very charming and most talented, Cilla has for the second time hit the number one spot in the British pop charts-something no girl has done since 1961.



Sharing her home town Liverpool with the famous Beatles, she was 'discovered, by Brian Epstein. Determined to sing her way to the top, Cilla told Pete Myors that she likes best good swing me... numbers but is happy to the sad songs if that is what her fans want. She says I love people and I like to be around them.

And her next recording, Cilla hopes will be a number by Beatles John Lennon and Paul McCartney 'It is the favourite' says Cilla, and no doubt a winner too.

LONDON FANFARE a magazine programme of news, viewe and interviews is heard weekly on Sundays by listeners to the BBC in West Africa.

# Nigerian Prime Minister Addresses Distinguished Gathering

LONDON — Today the Prime Minister of Nigeria is the guest of honour at luncheon given by the magazine "New Commonwealth". Also attending will be the Duke of Devonshire, Minister of State for Commonwealth Relations; Sir Kenneth Bradley Director of the Commonwealth Institute, Sir Paul Sinker, Director General of the British Council; Mr. T. Fife Clark, Director-General of the C.O.I. Arthur Clark Director of the Commonwealth Relations Office Information Services. Viscount Boyd of Merton (a former Colonial Secretary) and Mr. R Thomas, Under-Secretary of State, Department of Technical Co-operation.

The host will be Mr. A.E. Morgan Chairman of "New Commonwealth" who will introduce the Nigerian Prime Minister.

In the evening Sir Abubakar will be the guest of the Queen at a dinner party at Buckingham Palace.

For World-wide and Local News
**Read ELETI-OFE Weekly**
**News Paper**

## Omo Egbe Demo Wo Ijakadi Pelu Awon Olopa

(O bẹrẹ loju ewe keji)

A gbọ wipe ni alẹ ọjọ Aiku to kọja. Oloye Akinpẹlu igbakeji agba ọga awọn ọlọpa, Ọgbẹni E. Glaisher ṣe ipade kekere kan ninu ile Oloye Akintọla lori rogbodiyan na, ṣugbọn a ko mọ nkan ti nwọn sọ nibi ipade wọn na.



Oloye FANI-KAYỌDE

nje Alade Idanre, ọga on wa si ile on o si bẹrẹsi yọ iyawo on lẹnu, ẹniti on gba lọwọ rẹ lati bi ọsẹ diẹ sẹhin, o si tun dahun pe on gba ọmọge na lọwọ ọga on nitoripe o fẹran on ju ọga on lọ. idi eyi ni o ṣe na ọga on nitoripe o nṣe ayọnusi larin awọn mejeji.

Adele ọga adajọ Ọgbẹni A.O. Obilẹyẹ ti o ndajọ ninu kotu kekere na sọfun Akinṣọwọn ninu idajọ rẹ pe o jẹbi ẹsun rẹ pe o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sunun, nitorina on paṣẹ pe ki o lọ san poun meje-abọ (£7:10/-) lati fi tan ẹbi rẹ tabi ki o lọ ṣe ẹwọn oṣu kan pere ti ko ba ri owo san.

# Alhaji Dantata Fi Ogba Ewon Sile

EKO–Ọjọ Iṣẹgun ti nṣe ọjọ keje oṣu yi dabi ọjọ ayọ nla ati igbọwọ lọwọ ara ẹni ti ko lopin si awọn oluworan ti nwọn pejọ si ibudo ọkọ ofurufu ni Ikẹja fun atọjuba awọn arakunrin meji lẹhin ti ijọba ti da okan silẹ kuro ninu ọgba ẹwọn nibiti o ti wa lati ọdun 1957.

Awọn arakunrin mejeji na ni Alhaji Mahmud. Dantata ati Alhaji Sanusi Dantata ti nwọn ti ilu Kano wa si ilu Eko.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, Alhaji Mahmud Dantata ti ẹniti Gomina ipinlẹ Ariwa ni ile Naijiria Alhaji Ibrahim Kashim fi akekuru ọjọ ẹwọn ọdun mẹrinla ṣe laanu, ti o si sọ pe ki nwọn dasilẹ ki o ma lọ I sẹka na ti awọn alaṣẹ ile ọgba ẹwọn ti o wa ni Broad Street ni Eko ti ri iwe aṣẹ yi gba ni nwọn si ti fisilẹ pe ki o ma lọ.

Alhaji Sanusi Dantata ti ba ọkọ ofurufu wa si Eko lati ilu Kano ni ilẹ Hausa lati wa ba arakunrin rẹ

## Okunrin Kan Na Oga Re Lehin T'o Gba Iyawo Re Tan

AKURẸ— Gbogbo awọn ẹnjaati awọn enia ti nwọn pejọ sinu kotu Adajọ kekere kan ni ilu Akurẹ lẹnu lọọlọ yi ni nwọn bu si ẹrin nigbati akọwe awọn onisọwọ ti nwọn nra koko kan, ẹniti awọn ọlọpa mba sẹjọ lori ija ija sọ pe, on na ọga ti o gba on siṣẹ nitoripe ọga o ma nyọ on lẹnu nigbakugba lẹhin ti on ti gba iyawo rẹ tan.

Ọgbẹni a'ajangbula ti awọn ọlọpa mba sẹjọ na ni Claudius Akinṣọwọn, ẹni ọdun mẹrindinlogun nitoripe o ba ọga rẹ ja ija iwọsi, on na ni Ọgbẹni Samuel Adeyefa, eni ogoji ọdun ti o si tun ie enis wo to nra koko ati ekurọ.

Ninu ọrọ rẹ, o d ran na sọfun kotu pe ni ọjọ kejidinlogbọn oṣu kej la ọdun to kọja ni ilu kan ti o


**Never**

refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

*DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES - BENZ OR RENAULT CAR!*

MERCEDES-BENZ



**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 233.0; Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos.